Gbogbo ijọ mi ni wọn maa ṣọ kuro nibi aburu ayaafi awọn alaṣehan

Lati ọdọ Abu Hurayra - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Mo gbọ ti ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n sọ pe: «Gbogbo ijọ mi ni wọn maa ṣọ kuro nibi aburu ayaafi awọn alaṣehan, ati pe dajudaju ninu aṣehan ni ki ọmọnìyàn o ṣe iṣẹ kan ni oru, lẹyin naa ki o wa ji ti Ọlọhun si ti bo aṣiri rẹ, ki o wa sọ pe: Irẹ lagbaja, mo ṣe nkan bayii bayii ni alẹ ana, ti Ọlọhun si ti bo aṣiri rẹ ni alẹ, yio waa ji lati ṣi gaga aṣiri bibo Ọlọhun kuro».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe alaye pe dajudaju Musulumi ẹlẹṣẹ ni o ṣeeṣe ki o ri amojukuro Ọlọhun ati aforijin Rẹ, ayaafi ẹni ti o ba n fi ẹṣẹ han ní ti ṣiṣe faari ati jiję aṣa, oun o lẹtọọ si amojukuro; latari pe yio da ẹṣẹ ni oru, lẹyin naa yio ji ni ẹni ti Ọlọhun ti bo aṣiri rẹ, ni yio ba sọ fun ẹlòmíràn pe oun da ẹṣẹ bayii ni ana, ti o si sun ti Oluwa rẹ ti bo o ni aṣiri, ni yio ba ji ti yoo waa tu aṣiri bibo Ọlọhun lori rẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3756